# LOWO IKU OJIJI, OLUWA RERE GBAWA!

**Ikede**

Awe Ikede yi fun gbogbo ẹnyin Onkawe wa ati asoju wa wipe, ẹni kẹni ti owo ba sẹku si owo rẹ ki o tete fi ransẹ nitori gbogbo ohun elo ti a fi ntẹwe iwohin lo ti gbe owo leri.

Enikẹni ti ko ba fi tirẹ ranse ao da iwe rẹ duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C SERVES YOU WELL

VOL VII No. 427 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA AUG 6 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI (2d)

## ADEWALE—LOYA, SOJA, OSELU ATI OSERE.



THE BOY IS GOOD

Ogbeni Isau Sanni Adawale ti a nwo aworan re l'oke Iweyi je omo bibi inu Ologbe Sanni Adewale, "abiru-bamba afija-pomo-lekun-p'omlerin" okan pataki ninu awon Oselu Eko aiye igbani.

Ogbeni Isau, S. Adewale ko eko Iwe ninu Ilewe giga ti a npe ni C.M.S. Grammar School, ninu Ilewe ti a npe ni King's College lo ti pari eko iwe re, o si yege yekeyeke to fi je asiwaju awon omo akeko ilewe giga na ni odun 1937.

Nigbati o pari eko imo iwe re, o bere ise l'abe awon oyinbo Oloko Oju-omi (Marine Dept.), bi o ti je enia ti o ni ife ati ja fun anfani ati alafia ilu re to, o lo wo ise Ologun ti awon Qloko Ofurufu, (Royal Air Force) ninu odun 1943 lasiko ogun, o se to odun marun ki nwon to da won sile nigbati ogun pari.

Lehinna, l'o to bere si kose Loya, (Agbejoro) nilu Oyinbo ninu Ile eko nla ti a npe ni Lincoln's Inn. O yege fun ise Loya ninu odun 1951, o je pataki ninu opolopo egbe awon omo akeko nilu oyinbo, bakanna l'o tun je kosero ninu ere Bolu gbigba, tolowo-telese.

Awon ilu pupo lo ti de nilu awon Oyinbo bi Denmark, Sweden, Holland, ati Germany, O si ti ba awon oselu pataki-pataki pade ti nwon si jo lopo l'ofi ni imo yekeyeke nipa ise iselu.

E yan si i'e Igbimo apapo nla ti Nigeria (House of Representative) ko ni fi ehin yin da ogun, yio ja fun anfani olowo ati mekunnu ilu Eko.

E DIBO FUN ADEWALE.

The Boy Is Good

## Lowo Iku Ojiji, Oluwa Rere Gbawa!

Qjo ko nigbagbe ni ojo Alaruba (Wednesday) ti ise ojo keta osu August, 1955 yi je nilu Eko; ojo na ni Ogiri ehin Ile-iwe St. Peter's School ati Panu ile to wa lori re wo pa opolopo awon omo akeko, to si se opolopo lese.

Awon omobinrin merin ati omokunrin kan ni nwon fa yo l'oku l'abe ogiri, lehinna ni omokunrin meji tun ku ni Ile Iwosan (Hospital) apapo awon omo to ti ku je meje (7) awon mejidinlogbon (28) lo wa ninu ile Iwosan (Hospital) to fara sese.

Ilu Eko daru fun tokunrin-tobinrin awon obi omo, opopo Broad Street to fi de Ajele ni awon enia nwo tiree, bi enia ba fi oju ri wahala ati idamu awon obi omo bi oluware je ori ahun, perepere ni omije yio ma da loju oluware.

Awa Eleti-Qfe fi wosika wa yi ki awon obi omo ilewe na, awon to padanu omo won ki Oluwa Qba Olutunu masai tu won ninu, awon ti omo won f'arapa ki Olorun gbe won dide, ki Qlorun Olodumare maje ki a ri agbako jamba mo; Amin Ase.

WESTERN REGIONAL DEVELOPMENT BOARD

Lafia Canning Factory invite applications from a suitably qualified Nigerians, over 25 years of age for the following posts:-

1. DEPUTY ENGINEER: duties will comprise supervision and maintenance of canning machinery, steam raising plant, electrical and ancillary equipment. Only applicants with sound training, both theoretical and practical, in machanical engineering can be considered.

2. DEPUTY ACCOUNTANT: this post demands previous experience of accounting up to preparation of final accounts. A knowledge of cost accounting and stores systems would be an advantage.

3. ASSISTANT FACTORY MANAGER; who will assist with general administration, and should have previous experience in commercial organisation, in control of staff and knowledge of business methods. Since the factory operations are technological, previous engineering or scientific experience would be of value.

Applications giving full details of education, previous experience, age, and salary required should be sent to:-

LAFIA CANNING FACTORY,
PRIVATE MAIL BAG,
IBADAN.

not later than 20th of August 1955.

# ELETI QFE

EDITORIAL OFFICE & WORKS
23 Kosoko Street Lagos
P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS
"ETI-OFE LAGOS"
Phone 22370

VOL. VII NO. 427, LAGOS SATURDAY AUG 6 1955


## Wombiliki, Wobiya

Enia ni isora pupo l'ode aiye wa yi nipa ohunkohun ti enia ba nse l'aiye, ki o ma jeki iwa wobiya han ninu ise re,

Opolopo enia ni yio ro wipe nigbati a ba pe enia kan ni wobiya, yio so wipe, o ni okanjuwa onje ni. Sugbon a fe 'ki enyin okawe wa mo wipe ki ise onje nikan ni a le tori re pe enia ni wobiya.

Iwa wobiya mbe loto, isoro jade l'enu enia nfi wobiya oro han, bakanna ni ti onje paapaa je; nigbati enia ko ba mo iwontun-wonsi ninu ohun gbogbo, ojulowo wombiliki wobiya enia ni.

Nitorina, a fi wosika wa ose yi ta enyin okawe wa ji niba soki, ki a le ma sakiyesi ara ninu iwa hihu, oro sis..., ati onje jije. Aiko bikita fun nkan wonyi ni iso enia di wombiliki, wobiya.


## Irora Ni Orike ike Eti Isan Ara

BOYA ARUN IGBAROKO LOFA



Ise ti KIDINRIN tabi olo-inu nse ni lati ko gbogbo idoti ti o mbe ni ara danu, Bi awon Kidinrin nwonyi ko ba sise daradara awon idoti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.

Ona ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a se iranlowo fun Kidinrin lati sise re egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le sise na.

Nitorina iru arun bayi ni a sese egbogi ni o si je ... o si nfo inu enia mo nipa jije ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Opolopo iwe ni a ti ri gba lati odo awon ti arun yi mba ja, ti nwon si ti ri iwosan kiakia.

Kini nda o duro ti iwo ko danwo fun irora tire lo si sobu egbogi lo ra okan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ehin didun, Irora Orike Laku regbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Ohun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi je eyiti a se tonitoni gbogbo egbogi re lo si dara.



DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles



**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT :

## Okunowo Brothers

63, Massey Street, (Faji Market), LAGOS, NIGERIA.

The housewhere Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.



## Opportunity for ALL




The policy of The United Africa Company has always been to advance West Africans to positions of responsibility. To-day nearly one in four of the managerial trading staff is African. The Company is pleased that each year more Africans fill senior appointments in all branches of its organisation.

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LTD

## Ogun To Nlo Eran-Omi Jinna

Awon oyinbo Gesi lati ipilese isedale won, ise oko oju omi ni nwon nse. Opo si ni oko oju omi ti se jamba si. Ninu awon enia ti jamba sele si nwonyi opo ninu won lo je eniti ogbon ori re peye, tobe ti ko si iru awon enia be titi di oni.

Ohun ti o nse iku pa opo awon enia ti jamba sele si larin agbami okun ni Ekura yanyan, tabi ca Onida awon Gesi se kiri kan, ti a npe ni Afe (Life Belt) Ise re ni wipe, bi enia ba ja si omi ti ko mo iwe nibiti o gbe npe alu, abu, bi owo re ba te Afe na, ti o si dani, oluwa re ko ni ri lo sisale odo titi ti iranlowo yio fi de ba a.

Sugbon larin alagbalogbu omi okun, iye awon enia ti o ba lo Afe yi, elomiran a ma lo to iwon ojo meta tabi ose kan lori omi ki o to ri iranlowo. Ninu awon enia na ti jamba sele si bi nwon ba je Ogorun enia awon eran omi yio pa iwon adota enia larin won.

Nilu kan ti a npe ni Cadifu (Cadiff) nile Gesi lbe ni okunrin kan wa, ti oju re ti ri madomi-eran-nu ninu ise oko oju omi, On li eniti o ngbero lowo-lowo lati se egbogi kan ti yio je Aabo ati iranlowo fun awon Atuko oju omi kuro lowo ijamba yanyan, Ekura, Eja-Onida, Ese, Esin-omi, Abuibutan, ati Oni.

Egbogi na je eyiti awon Atuko yio ma so mo ese Lasko ti nwon ba mbe ninu omi, bi eran omi ba gborun re, afara ko si, eran omi na ko gbodo duro, bi beko yio di oku orun.

## Aditi Pariwo Ni Kotu.

**Eko** Okunrin kan ti oruko re nje John Franklin Floger ti o je aditi eni to nse ise akowe l'abe Alhaji Nassim Nogo, ni nwon fi sun esun pe o ji owo bi ponun merindinlogofa (£116) ti ise owo Alhaji Nassim Nogo.

Nigbati oro na de iwaju adajo, o so fun adajo wipe on ko gbo-oro nitoripe eti on di - sugbon ki nwon je ki on ka esun ti nwon fi on sun ninu iwe, adajo si gba be fun u.

Nigbati o ka esun re tan ninu iwe, ni o ba bere si k'igbe, to npariwo ninu apoti. Adajo ni ki nwon mu kuro ninu apoti, o si fi ejo re si igba miran, ko fi ojo si.

## Gari Di Golu Ni Igboro Eko

**Eko** Oro oja ohun jije di orisa akunlebo nilu Eko wa yi nisisiyi enia le gbo giriri-ojo ko da omi agbada nu? Ekun-owo awon osise ti Ijoba nfe se, koi ti se awon Oloja onje, papaa awon Onigari, ti o je ohun jije fun mekunnu enia ni won ti gbe owo re ga s'oke lati sile meji abo 2s 6d di sile meta-abo 3s 6d fun panu kan.

A ko tun le so ti awon ohun elo ti obe, bi eran, eja ati awon ata isebe pelu awon ivoku ti gbogbo won gbe'na owo l'ori. Eyi se kelebo awon enia wonyi ko tile ro ti ogunlogo enia ti ki ise onise Oba ti ko si ni ri ekun'wo gba.

O ye ki enyin enia wa fi ye denu ki e je ki ilu wa je irorun fun wa gegebi Oba Olodumare ti pese re fun wa

## Omo Oba Oni Di Dokita



Irohin idunnu ti a gbo lati Ilu Oyinbo ni wipe omo Alaiyeluwa, Olola - Nla Oba Adesoji Aderemi Oni Ile- - Ife ti o nkose Onisegun Iwosan ninu Ile Eko giga ti awon npe ni University ti Edingburgh nilu Oyinbo ti yege ise Dokita yekeyeke, o si ti gba oye ise na l'okunrere, M.B. ati Ch..B.

Dokita Omo'ba Ademola Aderemi yi lo si ilu Oyinbo ninu odun 1948, nigbati o de ilu Oyinbo, o koko ko ise alakobere fun ise Dokita fun odun kan ni ile Eko giga ti a npe ni Norwich City College

Lehinna, o wo ile Eko giga University ti Edingbergh ninu osu October 1949, o si pari eko re l'asiko ge e.

A ni ireti wipe Dokita Aderemi yio pada de si ile wa ninu osu September pelu ogo Olorun. Dokita Ademola Aderemi yi je omokunrin bibi inu Olola - Nla Alaiyeluwa Oba Oni ti ile - Ife ti ise Alakoso (President) Ile Igbimo ti awon l'oba - l'oba ti Ijoba Iwo - Orun, okan pataki l'o si je ninu awon Oba ile wa ni apa Iwo - orun ni Nigeria.

Awa Eleti - Ofe fi eyi ki Alaiyeluwa Sir Adesoji Aderemi Oba Oni ti Ile - Ife ku orire, ki Olodumare mu omo na de l'alafia.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo ewa ra Omorela O dara pupo fun awon omode

A mu je ki omode ri orun sun dandan, o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja nl'asiko ehin. Opolopo abiyamo l'o ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Qmorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

O wa lodo:

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST
10, Victoria Street Lagos


## Idahun Si Ibere Salako

Ogbeni Salako ara Yaba li o kowe si wa wipe, on gba ni imoran fun wa wipe gbogbo awon akiyesi Ijoba ati ipolowo oja ti o mbe ninu iwe irohin wa ki a ma te won lede Yoruba.

Eyi dara be nitoto, o si wu awa na papa a' sugbon Yoruba lpowe wipe sa a bi Onisegun ba ti wi.

Lati owo omo Oniku ni ere sise yio ti wa, iwe ti Ijoba ba nfe ki a te jade lede Yoruba, awon ni yio mu ase wa, sugbon nigbati nwon ko fun wa li ase lati te jade li ede miran nwon ko ni sanwo. Bi oro ti je niyen.

OLOTU

## Oloruka Gba Oruka Owo Awe Dofo

A gbo irohin kan bayi wipe okunrin kan ti o nse ise Oniwaya (Signaller) ni ilu Owerri ti oruko re njo Suisa King, ba odomobinrin Ibo kan se ore, de ipo ti nwon fun ara won loyun. Nigbati oro yi di mimo awon obi omodebirin na, nwon ranse si oko re ti nwon ti fi fun lati kekere wipe, iyawo re ti lo sowo omo o si ti jere, ki o tete wa gbe ni iyawo.

Omodebinrin na ko fe lati ni oko ti awon obi re fifun yi, o nfe fe Yoruba, Ogbeni S. King. Omo na gba Ogbeni King ni imoran wipe, ki o gbe on salo sile Yoruba. Nitori idi eyi, Ogbeni King kowe fun Transfer nitori on ko ni alafia nilu Owerri.

Nigbati esi iwe na de, ojo ti awon ma gbe omo na ni iyawo gan, ni Ogbeni King ni lati lo si ilu Agbor lati lo sise nibe King si ti seleri fun iyawo re wipe ki o fi okan bale on pelu re li o jijo ma kuro ni Owerri.

Awon egbe odomokunrin, omo Yoruba kan wa ni Owerri ti a npe ni Accra Fancy Club, nwon je omo Agan Ogbeni Suisa King ti lo be won lowe lati ba on gbe iyawo na sinu moto.

Lojo na, nwon ti mu iyawo lo si Sosi, gegebi asa ile won, bi nwon ba gbe yawo kuro ni Sosi, oko iyawo ati iyawo ylo ma rin, yio si ma yan loju opopo, awon obinrin yio si ma korin tele won lehin.

Bi nwon ti nse eyi lowo ni awon omo Agan yo si won ati iyawo ati oko iyawo o di pe ntuka, ni nwon ba gbe iyawo lo ba oko re. Oloruka gboruka, owo Awe dofo.

## Bawo Ni Ijoba Orun Tise Di Afagbara Wo?

Olotu,

Jowo gba mi laye lati se abere nwonyi lodo awon Onigbagbo ati awon Aladura ati awon Woli, ati awon Alakata-kiti wipe, kini fa gbolohun ede yi ti a ma nsaba gbo lenu awon Onigbagbo bayi wipe, ha! Ijoba Orun di afagbara wo.

(a) Tali eniti o so be?
(b) Tali eniti o lo si orun ni irowo-rose ti o tun pada wa wipe ko tun se wo ni irowo-rose mo.
(d) Kini ona ti nwon ngba wo ijoba orun nigba lailai fi yato si ti isisiyi.

Nitori Olorun Oba so pe, Emi li Enikanna lana, loni ati titi lailai, emi ko yi pada. E la a ye ni.

Emi ni,
Alfa Lemomu A...


# Dokita Fihan Wipe

## Ose Palmolive Le Jeki Ara Re Ro, Ki o Se Fulofulo Larin Ojo Merinla


Miss Yinka Olujare Nigeria Secretariat Student London

**Ewa jade lara mi nitoripe motele ilana ti Dokita se**




Epo Ile Afrika ni a fi se

COLGATE PALMOLIVE SOAP



# Always Read And Advertised In Eleti-Ofe

**ENJOY YOUR OWN SONGS**

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERING OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS O

OBTAINABLE FROM :

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA

## Idibo Dogun O Dude Ni Soba

Irohin kan wa wipe ijoba ile Yoruba ti fi ase si wipe ki awon Egun ni Igbimo tiwon loto, ki Awori ni tire loto. Awon apakan ninu awon ara Odan ti o mbe labe Awori ranse pe Ogbeni S. A. Abudu ki o pada wale fun yiyan si igbimo gegebi asoju awon ilu ti o mbe li Odan.

Sugbon nigbati o de ohun enu won ko s'okan. Apakan awon enia fe yan S. A. Abudu, awon elomiran yan Basiru Salami Dawudu.

Tele-tele Assist Electoral Offieer ti so wipe eniti o mo iwe, ti o si gbo ede Oyinbo ni nwon nfe ninu igbimo na, Awon ara Odan taku wipe eniti ko mo iwe ni awon nfe.

A fi eyiyi ke si enyin ara Odan wipe Ogbeni S. A. Abudu ni ki e dibo fun nitorire o ti mo nipa ise yi.

Iwo ha ti polowo Oja re sinu Iwe Irohin Eleti Ofe bi?

Iwe Irohin Eleti - Ofe kari gbogbo ile nile Nigeria ati nilu Okere.

Polowo Oja Re Sinu Re

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

Medicine Store
7, Egerton Road, Lagos

**NOW, AVAILABLE**

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS DISTEMPERS, SAFES Etc.

Just write, Call, or Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street, (P. O. Box 395) Lagos, AND NEW COURT ROAD IBADAN

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charm Mohammedan charms, Amulets Vedic Prayers, Kowachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 19 Bessborough Garden, Westminster, London, S.W.1. England

FEDERAL ELECTION
AUGUST 11, 1955
Vote For Adewale
(The boy is good)

## Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

### LOSAN. ATI ORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.





OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun ehin te, awon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyi ti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.

Sodium N-Lauroyl Sarcosinate

SAME FAMILIAR PACKAGE!




Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

# O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Eni Baje.

## E Dibo Fun Adewale




## Akiyesi

Enikeni Ti O Ba Nfe Ra Iwe Irohin Eleti-Ofe Nilu Tamale Ati Agbegbe Re, Kio Lo Si Qdo:-

QGBENI RAJI ALAGBE
House No. H 75. Tabi Tamale
Central Market
P.O. Box 95,
TAMALE

**HAPPINESS SUPREME!**




"Ma gives me "BANWO" and so, I'm strong, robust and healthy."

Buy BANWO for your babe
large bottle 4/6. small bottle 2/6
Postage extra. Ask for wholesale price.
THE IBADAN STORES P.O.Box 1 I.B
and branches.

## AWO IKORIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

**Lo ra won ni sobu**

**S. C. O. A**

A ti da Eka titun kan sile ti yio tete ma fi awon eru ti o se pataki ranse.

**S. C. O. A.**

Head Office:- 40 Marina Lagos
Show Room Martins/Broad Street Lagos
ATI NI
Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370